**Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School**

**Ose Kokanla: Osu Keta, Ojo Kejila, 2017**

**Akori oro: Ironupiwada** - Apa Keta

**Eko kika: Joeli 2: 12-17**

Ki a to tesiwaju, mo fe lati ran wa leti pe ki a ronupiwada, ki a si wa Oluwa ni igbati a le ri i: ki a si pe nigbati o wa nitosi, ki akoko ironupiwada to koja lo **Isaiah 55: 6.** Eko yi ntesiwaju nigbati ao soro nipa awon imoran ninu Bibeli si ironupiwada.

## IMORAN ATI IGBANI-NIYANJU

Ao soro nipa igbani-niyanju ti a ko sinu oro Olorun, ti o le to wa si ona lori ironupiwada.

**WASU IRONUPIWADA FUN AWON ENIA:** Kede jake-jado agbaiye, pataki-julo fun awon keferi wipe ki won ronupiwada, ki won yipada si Olorun, ati-pelu ki won ma se ise ti o ye si ironupiwada **ISE AWON APOSTELI 26: 20.** O je ojuse re lati wasu ironupiwada ni gbogbo aiye, ki awon enia le ronupiwada awon ese won, ki won si yipada si Olorun; ki won si se afihan ironupiwada won nipase ise rere won.

**MASE FI AKOKO ATI IPA KRISTI SOFO:** Niwon igbati Jesu wa lati lati pe awon elese si ironupiwada, ti iwo si je okan lara won, ronupiwada ni kiakia, mase fi akoko, ipa ati laala Kristi sofo **MATTEU 9: 13, MARK 2; 17, LUKU 5: 32.** Kiyesara mase mu Olorun binu nipa fifi akoko Olorun ti o sowon sofo.

**MASE SE OHUN TI KO LETO:** Ara ninu Oluwa, e mase se awon ohun ti ko leto, sugbon e ranti bi e ti se gba a ati bi e ti se gbo Ihinrere;

ki e di mu sinsin, ki e si ronupiwada; bikosebe Kristi yio yo si o bi ole, nigbati iwo ko lero **IFIHAN 3: 3,** Niwon igbati o mo wipe Jesu yio yo si o bi ole, ronupiwada lesekese.

**MASE SE KRISTI:** Opolopo enia ni won njewo wipe awon mo Jesu Kristi, sugbon nwon nse Oluwa nipase ise owo won. Iru awon enia wonyi ni Bibeli wipe awon ti a ti la loju lekan, ti nwon si ti to ebun orun wo, ti nwon si ti di alabapin Emi Mimo; **ti nwon ba subu kuro loju ona otito ko le se ise lati so won di otun si ironupiwada**, nitori won tun kan Omo Olorun mo agbelebu si ara won ni otun, nwon si dojuti i ni gbangba **HEBERU 6: 6**. Bi o ba wa lara irufe awon enia wonyi, jowo mase dojuti Kristi, ki o maba nira lati mu o wa si ironupiwada, ni eyiti o ba sonu ninu aiye re, iwo ki yio le jogun Ijoba Olorun.

**MASE KUNA ORE-OFE LATI RONUPIWADA:** Kristi ti fun o ni ore-ofe lati ronupiwada loni, jowo mase kuna ore-ofe yi lati yipada si Olorun ki o si ba Eleda re laja. Awon enia Tiatira ni iru ore-ofe yi sugbon won ko ronupiwada **IFIHAN 2: 18-21.** Mase kuna lati lo akoko ore-ofe yi lati ronupiwada, E mase dabi Esau, eniti ko ronupiwada sugbon o nfe lati jogun ibukun Abrahamu. Bibeli wipe " eyin mo wipe lehinna, ni igbati Esau nfe lati jogun ibukun baba re a ko o, nitoripe ko ri aye fun ironupiwada atipe o ti pe ju fun ironupiwada; bi o tile bebe ti o si wa ibukun na pelu omije **HEBERU 12: 16-17.**

## AWON IJIYA

Ao soro nipa awon ijiya ti nduro de awon enia ti ko ronupiwada, bi won ba ko lati ronupiwada logan, ki won si yipada si Olorun.

**ISI-NIPO OPA FITILA:** Bi o ko ba fe wa ninu okunkun aiyeraye, dekun iwa buburu re, ki o si ronupiwada ohunkohun ti o nse ti o nmu

ki awon keferi ma so oro-odi si oruko Oluwa lati ipase re. Bibeli wipe "Ranti ibiti iwo gbe ti subu, ki o si ronupiwada, ki o si se ise isaju; bi ko si se be, emi o si to o wa, emi o si si opa fitila re kuro ni ipo re, bikose bi iwo ba ronupiwada" **IFIHAN 2: 5.** Bi o ko ba fe ki a si opa fitila re kuro ni ipo re, ronupiwada, ki o si pada si ife-akoko ati awon ise-isaju re ti inu Olorun dun si. Se'ra fun ohunkohun ti o nse ti ko se itewogba ni iwaju Oluwa.

**KRISTI YIO FI IDA ENU RE BA O JA:** Yera fun awon ohun ti o nse ti o ko le kede won ni gbangba ita. A kowe re wipe o ni lati ronupiwada awon ese re, bibeko emi o si fi ida enu mi ba o ja ni Oluwa wi **IFIHAN 2: 16.** Ronupiwada ki o si dekun ohun gbogbo ti o nse ti ndojuti esin Kristiani, ki Kristi maba fi ida enu re ba o ja.

**IDAGUNLE SORI IBUSUN**: Ayafi bi o ba ronupiwada awon ise re, ao gbe o so si ori akete ni Bibeli wi. Bi o ko ba fe ki a da o gunle si ori akete, siwo awon iwa ti nko egbin ati idoti ba eri-okan re niwaju Oluwa **IFIHAN 2: 22.** Ronupiwada, ki o si dekun awon iwa-ikoko ti o lero wipe kosi eniti o ri o, tabi ti o mo nipa re; bibeko, ao gbe o so si ori akete aisan.

**IDALEBI NBE FUN AWON ALAINI-IRONUPIWADA:** Awon enia ti won ko ronupiwada nipase iwasu Jesu Kristi ati eko yi ni ao da lejo. Niwon igbati awon enia Ninefe ronupiwada awon ese won nipase iwasu Jona, nitorina won yio dide pelu iran yi ni ojo idajo, won yio si da lebi **MATTEU 12: 41, LUKU 11: 32.** Bi o ko ba fe ki a da o lebi, ronupiwada loni nipase oro Kristi yi ti a ran si o.

**AWON ALAINI-IRONUPIWADA YIO NI IBANUJE-NLA**:Irufe awon enia wonyi yio ni ibanuje-nla, nitoripe won ko ronupiwada bi o tile-je wipe Oluwa ti se awon ise-nla ati awon ise ti o ni itumo ninu aiye won. Awon wonyi yio ni ibanuje-nla nitoripe ibasepe a se iru awon ise wonyi ninu aiye awon elomiran, won ko ba ti ronupiwada

tipe **MATTEU 11: 20-21**. Bi o ko ba fe ipayin-keke bikose ayo ninu aiye re ronupiwada loni.

**OWE AGAN IGI OPOTO:** Okunrin kan gbin igi opoto sinu ogba ajara re, gbogbo igba ni o nwa lati ka eso ni ori re sugbon kori eso ka. O duro fun odun meta, sibe igi na ko so eso. Nigbana ni olusogba be e, wipe ki o fun on ni odun kan si, ki on le tu ile-idi re yika, ki on si fi iledu si pelu. Bi o ba so eso on yio ma se itoju re; sugbon ti ko ba so eso, kike ni ao ke lule **LUKU 14: 7-9.** So eso ti o ye fun ironupiwada, bikosebe ao ke o lule, iwo yio si segbe.

## Christ Apostolic Miracle Ministry Sunday School

## Ose Kejila: Osu Keta, Ojo Kokandinlogun, 2017

## **Akori oro: Ironupiwada** - Apa Kerin

## Eko kika: Joeli 2: 12-17

### <u>Awon akoba fun aini ironupiwada</u>

A ni lati mo wipe ironupiwada ni ohun ti o daraju ti o le sele si eda-enia, atipe ohun nikan ni ona lati mu ogo ti awa eda-enia ti sonu pada-bosipo. Ni alaisi ironupiwada awon nkan ti ao menuba yio sele:

- Aiye enia yio dojuru, besini irinajo enia yio si baje tabi ki o segbe.
- Eda-enia yio wa ni oko-eru nipa Emi, besini okunkun yio si ma joba lori awa enia tabi se akoso aiye awa enia.
- Enia koni ni anfani lati darapo pelu awon eda ti orun tabi ki o ri awon ebun Emi Mimo gba.
- Idajo gbigbona Olorun yio wa si ori awa eda-enia, besini ao pari irinajo wa si odo Satani.
- Eda-enia ko le wu Olorun, tabi te Olorun lorun, besini eda-enia ko le se itewogba ni iwaju Olorun.
- Oro-agbara Oluwa yio di yepere ati alailagbara ninu aiye wa, debipe ko si enikan ninu wa ti yio wo ile-ologo.
- Eda-enia ko ni gbile tabi se aseyori ninu awon ona ti Esu la kale fun won.
- Irora/inira Jesu Kristi Oluwa ati iku-oro re lori igi agbelebu yio je lori asan.
- Majemu Olorun ko ni gbile ninu aiye awa enia, besini awon ileri re ko ni wa si imuse.

Fun awon idi wonyi, ronupiwada ki o si se ife Olorun.

## Itura fun awon ti o ronupiwada

Omo enia, ko Esu ati awon ise re sile. Siwo gbogbo iwa buburu re, besini ki o takete si olukuluku ise ibi.

- Ronupiwada loni, yipada si Olorun besini ayipada-otun yio sele ninu aiye re.
- Ronupiwada nisisiyi, ki Olorun ba le fi oju fo awon ese re ati awon asise tabi irekoja ojo pipe.
- Ronupiwada kiakia ki Olorun le so aiye re di otun, ki o si mu ogo ibere-pepe re padabo-sipo.
- Ronupiwada, ki o si ba Eleda re laja ki akoko to koja lo, ki o ma ba se aini ohun rere ninu aiye re.

## Awon ere ironupiwada

Olorun ko wipe ki o ronupiwada lasan, sugbon o ni opolopo anfani ti yio fi fun o, eyiti yio mu itesiwaju ati igbega ba aiye re; bi o ba le ronupiwada loni.

**Idarijin ese ati igba itura:** Ona kan ti o fi le ri idarijin awon ese re gba ni ki o ironupiwada, ki o si wasu ironupiwada fun awon enia jakejado agbaiye. Nigbana ni Olorun yio fi oju fo awon ese re, ti yio si darijin o **Luku 24: 47**. Nitorina ronupiwada, yi okan ati ipinnu re pada; yipada, ki o si pada si odo Olorun, ki a le pa awon ese ti olufisun fi njare re niwaju Oluwa re; ki akoko itura ba le ti iwaju Oluwa wa **Ise awon Aposteli 3: 19**. Bi o ba nfe idarijin ese ati igba itura, ronupiwada loni, ki akoko to koja lo.

**Idande ati iye:** Olorun yio bojuwo awon enia ti o ronupiwada, yio si da nwon nide **Luku 1: 68**. Dajudaju Olorun yio da nwon nide kuro ninu ese won gbogbo ni Bibeli wi **Orin Dafidi 130: 8**. Nitorina, e ma se rere ni gbogbo igba, ki e si takete si awon ohun ibi; ki Olorun awon omo-ogun le wa pelu nyin **Amosi 5: 14**. Lati isisiyi lo, wa Olorun pelu

okan-ironupiwada, iwo yio si ye, ni Oluwa wi **Amosi 5: 4**. O nilo okan-ironupiwada lati gba idande ati lati gbe igbe-aiye ti o ni itumo.

**Anu ati imubo-sipo:** Ko si Olorun kan ti o dabi Eni Mimo Israeli, ni oke orun, tabi ni isale ile, ti ipa majemu ati anu mo fun awon ti nrin niwaju re pelu okan-ironupiwada ni Iwe mimo wi **1 Awon oba 8: 23**. Nitorina, e wa, e je ki a yipada ninu ironupiwada si Oluwa, ki o ba le mu wa padabo-sipo **Hosea 6: 1**. Fun anu ati imubo-sipo lati farahan ninu aiye re, o nilo ironupiwada.

**Abo ati iyipada-otun:** Ronupiwada lesekese, bi o ba nfe:

- Lati gbagbe osi re, ti iwo o si ranti re bi omi ti o ti san koja lo.
- Ki ojo aiye re mole ju osan gangan lo.
- Wa ni ailewu, ninu ireti ati isinmi li alafia.
- Dubule ni aisi eniti yio deruba o, ti opo enia yio si ma wa oju-rere re **Jobu 11: 13-19**.

**Iwo yio ni opolopo ohun rere:** Bi o ba nfe ki awon ohun rere ki o je ipin re, ti o si nfe anito ati aniseku ire ki o farahan ninu irinajo re. O ni lati gboran si Oluwa lenu, ki o si ronupiwada ni wakati yi **Isaiah 1: 18-19**. Fun ire-ailopin lati sawari aiye re, o ni lati ronupiwada.
**Ibunkun ati isodi-pipo:** Bibeli wipe, ibukun wa li ori awon olododo, se awon ohun ti o leto, ki o si ronupiwada awon ese re; ki opolopo ibukun ba le farahan ninu aiye re laisi idiwo **Owe 10: 6**. Ki ibukun ibere-pepe ba le ni itumo ninu aiye re, o nilo okan-ironupiwada **Genesisi 1: 28**. Bi o ba npongbe lati jogun awon ibukun Abrahamu, o ni lati wa Olorun, ki o si ba a rin pelu okan-ironupiwada. Bi o ba fi itara wa Olorun pelu okan-ironupiwada, bi iwo ba mo, ti o si duro sinsin: nitoto nisisiyi ni Olorun yio taji fun o, yio si so ibujoko ododo re di pipo **Jobu 8: 5-6**. Kose-mani ni ironupiwada, fun ibukun ati aseyori lati jeyo ninu aiye re.

**Ebun Emi Mimo:** Peteru wi nipa isipaya Emi Mimo pe "Gbogbo enia

ni lati ronupiwada awon ese nwon, ki nwon yipada si Olorun, ki a si baptisi olukuluku li oruko Jesu Kristi fun idarijin ese nwon; lehin na ni nwon yio gba ebun Emi Mimo" **Ise awon Aposteli 2: 38**. Mase tan ara re, o di igbati o ba ronupiwada awon ese re, ki o to le gba awon ebun Emi Mimo. Bi o ba si ti ni awon ebun, laisi wipe o ronupiwada, ao gba won lowo re, ao si fi fun aladugbo re ti o ronupiwada.

**Iwo yio jogun ijoba orun:** Bibeli wipe, "Bayi li Oluwa awon omo-ogun wi; Oluwa awon omo-ogun wipe, e yipada si mi, emi o si yipada si nyin, ni Oluwa awon omo-ogun wi". Bi o ba yipada si Oluwa pelu okan-ironupiwada, On na yio yipada si o, yio si fi ijoba re, ti ise ijoba orun fun o **Sekariah 1: 3**. Okan-ironupiwada yio mu ki ara ya Oluwa lati fun o ni ijoba re, nitorina mase da-ara-duro, sugbon ronupiwada nisisiyi ki o le jogun ijoba Olorun.

"Wo emi fi ibukun ati egun siwaju nyin loni; ibukun bi enyin ba gba ofin Oluwa Olorun nyin gbo, ti e si ronupiwada awon ese nyin loni; ati egun bi enyin ba ko lati mu ase/ofin lati ironupiwada se" **Deuteronomi 11: 26-28**.

Lakotan, gbogbo awon ti emi ba fe ni mo mbawi, ti mo si nna: nitorina ni itara, ki o si ronupiwada, ni Oluwa wi **Ifihan 3: 19**.

**Edidi: Hosea 14: 1**:
Eyin kristiani, e yipada si Oluwa Olorun nyin, nitori enyin ti subu ninu aisedede nyin.